Secretary to the Government
Lagos


# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead.

Vol. III. No. 131. SATURDAY, JAN. 17, 1925. Fourpence.

***This Week's Circulation 1,500.***


20 JAN 19
LAGOS


## DURO THOMAS.

55, MASSEY STREET, LAGOS, (NIGERIA.)

P.O. Box 374. Telephone No. 243.

*The Best House for every Description of German Goods*

**"Specialities: Enamelware Beer, Wine, Iron Bedsteads, Ruby Plates, Rubber Beads of all kinds, Clay and Briar Pipes, Champagne, Cement, Biscuits in cases, Gun Powder, Wire Nails, Rangoon and original Ballam Rice, Accordeons, Piano, Padlocks, Beads, etc., etc., etc."**

---

## N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.

OYINBO **J. F. SICK**

Ọba Ilẹkẹ, Ile Ilẹkẹ, 9, Ita 'Bode lailai, Eko.

A jẹ Ajirera ninu òwò Ilẹkẹ, orişirişi Ilẹkẹ wọnyi wa ni tita:—

Ilẹkẹ Oyinbo, Ilẹkẹ Rubber, Ilẹkẹ Olomi Wajì, Ilẹkẹ Onikẹkẹ, Ilẹkẹ Elejo, Ilẹkẹ Ayinrin, Ilẹkẹ Oniwõrò ati Fadaka, Ilẹkẹ Kerewu, Ilẹkẹ Jòjò, Ilẹkẹ Òlokuta, Ilẹkẹ Oloruka, Ilẹkẹ Ẹlẹranko, Ilẹkẹ Didan Yinrinyinrin, Ilẹkẹ Meremere, Ilẹkẹ Mọjọkun, Ilẹkẹ Adumādan.

Ẹ wa wo Ile ọja wa; A ni nkan wọnyi fun tita:—

Ikoko Taba Onigi, Jigi, Aşọ Aran, Ẹrọ Agbado, Ife, Ọti Eleworo (*Beer*) ati Eleso Ajàrà (*Wine*), Awọn Onjẹ Ipanu, Aşọ Iş'oşọ, Ẹrọ Ere Ọmọde, Ohun Ọşọ, Abẹlà (*Candles*) ati ẹgbagbeje ọja miran.

A nta Maşini *Vesta*, a si ni *Cement* atata ti Portland ati Irin pipọn abẹ oni *Diamond*. Idi òwò wa wa ni Rotterdam, a si ni Ile Owo ni:— Calabar, Gablonz (Czecko-Slovakia) Gold Coast, Accra, Lome Hamburg, London, Venice (Italy).

# Lever Stores

# HAS NOW

# RE-OPENED

# WITH A FINE LOT

OF

# NEW YEAR

# GOODS.

*Editor & Proprietor*—
ADEOYE DENIGA,
*Offices:* 22 & 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

—o.—

ẸNI A NPERI KO TO NKAN !

Oriki ti o yẹ Oyinbo *Lord* Leverhulme Igi Owo ti t'ọmọde t'agba nṣ'afẹri ati mọ lati ọjọ to ti wọ ilẹ yi, l'eyi ; a ṣ'alabapade jagun na ni'le òwò rẹ Olowo S'oke Di'lẹ "*Lever Stores*" ni aṣalẹ *Monday* ọsẹ yi ni Opopo-nla ; gẹrẹ bi o ti yi wọ'le ni awọn ọgọrọ enia ti mọ pe "irẹ nrùn" eyini ni pe nwọn mọ pe ẹniti o daba pe on ma fi owo lu *Nigeria* pa nipa pipete ati rã lo wọle nì ; awa na ko fẹ ki nwọn gbe e s'ẹhinkule wa, nitori bi o ba ngbọ gbẽ gbẽ gbẽ, ṣe ẹnyin na mọ ibiti nwọn yio gbẽ si bo tete ba nwọn gbẽ ? Bi adiẹ ko sọ'kà a ti ṣe ṣọ́ si àgbàlá ile na, eyiti a nwi yi ti pẹ, oju t'awa t'Igi Owo na ṣe mẹrin, a wa mikanlẹ wayi o, pe ajo ati mọ owo Olowo s'oke di'lẹ wa kò lọ lasan ; nṣe ni a bẹrẹ si wò niti awòd'oro t'epiyà o jẹ alagba gidigidi, o si jẹ ẹni ọdun mẹtaleladọrin ; enia kukuru ni "Bilisi" akẹtẹ irufẹ kanna ni t'awa tirẹ jọ de, iyẹn ni agbõrùn funfun gbõ *(Helmet)* eyi iba jẹ le jẹ ki o fi nkan bi ẹgbẹgbẹ un pọun ọna igba jù wa lori nkọ ? Ṣe a ta yọ̀yọ—o wọ̀ aṣọ *Serge Khaki*—eyiti awọn ẹlẹwọ̀ miran ka si aṣọ ọbun, a ko to sọ eyi tan jade l'ẹnu o ! bẹni Jagun na nsọrọ mẹsan-mẹwa ti awọn Abẹyọ rẹ si rọ̀gbà yi i ká ti nwọn nwipe *yes ! yes ! !* ti nwọn si nmi ori wọn gbogẹgbogẹ bi ẹnipe o ma kan si'lẹ si ọrọ ti o nsọ. Kai, owo nipa ; ina njo, o nfẹ, o to iwọn iṣẹju melo kan, bẹni Ẹlẹgba ọmọ Asẹyin yan jade kọ-nduko-ndu o di inu mọto rẹ, o nwo ẹgbãgbeje awọn enia ti nwọn wa lati mọ ọ, lọgan a si agbọ pẹ-pẹ-pẹ, kilode yẹn ? Awọn Oyinbo ti nwọn ti kẹ pakute wọn silẹ dõ—ani pakute *Photo* lo bẹrẹ si ya fọto rẹ firifiri bi o ti kuku bọ s'ode ; Oyinbo kan tilẹ kọ'di si apa ile Captain Davies lailai, o si mu fọto tirẹ yi—eyiyi ni sinima *(Cinema)* bi o ti kuku ṣe wọ̀ sinu mọto rẹ, o di mẹrẹn, bẹ ni o na ya s'oke Olowogbowo ; awọn ṣaṣawẹrẹ ati agbalagba diẹ si ho iho ayọ. A gbọ pe o sọ pe ibiti Ile-òwò on *( Lever Stores )* wa kere ; o nfi oju ilẹ ilu rẹ ni *England* ti a npe ni *Port Sunlight* nibiti nwọn gbe nṣe ọṣẹ ti o nta fun gbogbo agbaiye, ilẹ eyiti ọrẹ wa Oyinbo Aṣoju rẹ nibi sọ fun ni pe o fẹrẹ to gbogbo Eko ni titobi, wo ilẹ wa nibi.

Ni gasikiya owo dun ni lọwọ, ko ṣe ni lọrun.

BẸ BẸ NI KA MA RI O—AṢẸ.

Kosi bo tiri ni *Dinner* ti a pe fun ẹyẹ Iwe-irohin wa "*Eko Akete*" ni ile onjẹ *Bonanza* ni'ta Ibode lailai *(Custom Street)* ni *Friday* ọsẹ to kọja.

Alagba wa Ọgbẹni J. H. Doherty ti a pete ati yẹsi lalẹ ọjọ na, ko le wa nitori ọfọ kan to ṣẹ ẹ ni ọsan ọjọ na gan a, ṣugbọn gbogbo awa to pe'sẹ sibẹ lalẹ na, da nkan ni'de.

Ọrẹ wa Ọgbẹni Duro Thomas A-l'ọwọ sinu-iṣẹ-rere-ṣ ṣe la fi ṣe Alakoso ariya yi o si sọ ba-nsa ọrọ.

Ọgbẹni Oluyẹle Bright ni ki nwọn fi le on l'ori te ninu agbeka ọrọ ti o sọ bi ilẹ bi ẹni.

Bẹ si ni Ọgbẹni L. O. Thompson igbakeji Alaga sọ t'ẹnu rẹ. Kini a le wi si ọrọ Ọgbẹni B. Ade Mumuney bikoṣe pe ṣe gbogbo wa ni ṣeranwo nigbati o nsi ọ tirẹ lawẹlawẹ, awa na papa bi *Editor*, "*Ek*

*Akete*" fi ẹnu gbun ọrọ ni'ba jaba riti ọmọde.

Wò mi ná ẹnikeji o gbà fun awọn ti o se eyẹ alẹ ọjọ na. Diẹ ninu awọn to wa l'eyi lẹhin awọn ti a ti daruko wọnyi :—

Awọn Ọgbẹni Alfred Williams, N. A. Ṣoluade, Alufa Ẹni-ọwọ A. A. Puddicombe Omidan Ebun Williams, D. Ayọdele Bright, J. Tade Bright, Olufẹmi Blaize, S. A. Johnson, Abraham John, Arthur Mayne ati ọgọrọ awọn Bọkinni miran. Aṣeyi ṣ'amọdun o. Aṣẹ.

KABỌ O, ỌMỌ LIGEGẸRẸ.

Ọgbẹni C. C. Adenẹye Titcombe Akọwe aṣiri ti Alake, de silẹ yi l'ẹnu ọsẹ yi.

ỌLAYIMIKA, ADEYẸMỌ, Ẹ KU AFẸKU !

A ba awọn ọrẹ wa awọn Lọya Ọlayimika Alakija ati Adeyẹmọ Alakija ati gbogbo awọn ẹbi, daro iku ẹgbọn ati iyekan wọn, Ọgbẹni Jiberu Alakija Onigbanjo Oke-odo ti o t'ẹrigba'sọ ni alẹ *Sunday* ọsẹ yi. Ki Baba rẹ nyin l'ẹkun !

AYA ALUFA JAMES PEARSE, M. S. COLE, J. A. COLE ATI ỌGBẸNI J. K. COKER Ẹ KU ỌFỌ.

A ba awọn aya Alufa James Pearse, M. S. Cole, J. A. Cole ati J. K. Coker k'ẹdun iku Ọgbẹni Dan Cole ti o nṣiṣẹ ni ọgba *Railway, Stores Department* ti o ngbe *Church Street*, Ebute Mẹta ati iyawo rẹ ti a npe ni Sẹgilọla ni oru fẹrẹkilẹmọ ọjọ kẹtala Atalata, *Tuesday* ti t'ọkọ t'aya filẹ bora ni ọjọ kanna, ọmọ nwọn ti a npe ni Richard Cole ti o ku ṣiwaju baba rẹ ati iya rẹ ni Alaruba ọjọ keje oṣu yi, ati ọmọ awọn agba obinrin ti ara rẹ ko da pupọ nwọn si gbe e lọ si Ọgba-alarun. Ki Oluwa Ọbanginji gbe nwọn si afẹfẹ rere, ki alaisan dide ninu aisan. A ki ẹnyin ẹbi ku ọfọ ajalu nla yi, ki Baba fori jin wọn.

A YỌ FUN Ẹ, A YỌ FUN ARA WA.

A ba Ọgbẹni Babatunde Coker, Dawodu Ọgbẹni S. Alfred Coker (Ologbe) yọ fun ẹni ọdun mẹrinlelọgbọn ti o da ni ọjọ kẹrinla oṣu yi.

KILẸ NṢE TI Ẹ PỌ TO YI?
IYAWO LA NGBE O!

A gbe omidan Marian Yetunde Pearse aburo Ọgbẹni G. B. Pearse ti *40*, Ereko *St.* Olori Iriju ni *Church Brotherhood* l'Eko nibi ni'yawo fun Ọgbẹni C. W. R. George ni *Church* Ebute Ero ni arọ *Thursday* ọsẹ yi ni agogo mẹwa.

Iyawo a bi'sun a bi'walẹ o.

WO'BI ẸNIKEJI

A o ṣe Isin iyasimimọ ti Ina mana-mana (*Electric Light*) ti a ṣẹṣẹ ta si Ile Isin wa ti ọmọ Ibilẹ (*Jehoval Shalom*) ni aṣalẹ oni ni agogo meje. Igbakeji Alabojuto Agba ni yio ṣe isin na. Akanṣe Iwe orin fun tita tọrọ (*3d*) fun ọkọkan.

Gbogbo nyin la pe tọkantọkan

---

**Stop Press !**

Ven. A. W. Smith, B.A., Archdeacon of Yorubaland, appointed Assistant-Bishop-Designate for Northern Provinces, Nigeria.

*Eko Akete* Wireless.

---

ỌWỌ A RAN A O!

O jẹ didun inu wa, lọpọlọpọ lati ri gẹgẹ bi awọn ọdọmọde Imale Eko ti ni ifẹ fun irẹpo larin arawọn ati lati ri gbogbo wahala ti nwon nṣe lẹnu ọjọ diẹ wa lati da Ẹgbẹ nlanla kan silẹ larin Imale ti yio ko ẹnu gbogbo wọn jọ ti ko si ni ni ohunkohun lati ṣe pẹlu igbagbọ (*creed*) tabi ijọ (*denomination*) ẹnikẹni.

Gbogbo eyi jẹ ohun to dara pupọ ; ṣugbọn ọna wo la o gba ti yio fi ṣeṣe ? A fẹ ki awọn ti o dawọ le iṣẹ yi mọ dajudaju pe iṣẹ kekere kọ arara ki a to mu Jamat, Ahmadia, Alalukurani, Koṣeyọ fi oju kan arawọn a ni lati ri ogun ti a le sa si ẹtu ti on pẹlu ina le fi di ọrẹ. A ko fi eyi ja nwọn l'aiya

(*discourage*): ṣugbọn a fẹ ki nwọn mọ ohun ribiribi ti o wa ninu rẹ ni. Ọgbẹni Adamu Animaṣaun pẹlu awọn ọdọmọde Imale pataki pataki li agbọ pe o nṣe pa a mu erọ na; a si gbọ pe nwọn ti ṣe ipade bi mẹta ni Ọgba Sinima Saka Baṣọrun ni Ita *Victoria*. Satide oni ni agbọ pe nwọn nko ritiriti na lọ ba Ọgbẹni L. B. Agusto B. L. Ọkunrin papa, ẹniti o fi ori ijọ Ahmadia sọlẹ silẹyi ti o si jẹ pe mimọ nipa Eto Ẹgbẹ ninu Ẹsin nho lori rẹ.

Ọwọ a ran a o!

GBARUKU.

---

## What! A Klu Klux Klan?

On Saturday the 10th instant at a meeting held at the Glover Memorial Hall, Dr. John Randle, in answer to a question by Mr. J. Akiyemi Oshodi, explained that his colleagues and himself thought that Mr. Macaulay's name should not be included in the Committee because he is a permanent foe of the Government.

### WHAT WE SAY.

But we are in a position to assert that the local Administration has the greatest regard for the ability, capability and local influence of Mr. Macaulay as the following correspondence amply testifies.

His Honour the Lt. Governor issued on the 27th September 1924, the following circular letter on the subject of the Yaba acquisition to a few gentlemen including the Hon. the First Lagos Member :—

"Dear Sir,

In view of the Acquisition Notice contained in the *Nigeria Gazette Extraordinary* of September 20, covering a large area of land in the direction of Yaba, I would be glad if you could make it convenient to attend a meeting at my house at 10.30 a.m., on Wednesday next October 1, when I propose to put before you the proposals of the Government in connexion with this acquisition so that there may be no misconception with regard to them, and at the same time ask for your criticism and advice.

2. I have confined the invitations to the meeting to the Honourable Members for Lagos on the Legislative Council, the Elected Members of the Town Council, and the Editors of the principal Newspapers published in Lagos. I quite realise that this may exclude a number of prominent citizens who would also wish to be kept informed of the situation, and I would welcome the presence of any gentleman you might wish to bring with you to the meeting, and would be glad to know, when you acknowledge this invitation, the name of the gentleman you propose to bring."

In his reply, the Hon. Mr. Shyngle embodied the following paragraph on the 29th September :—

"With regard to the extension of your Honour's invitation under paragraph 2 of your Honour's letter under reply, I propose to bring with me to the meeting, in view of the importance of the subject as touching the Land Question, Mr. Herbert Macauley, Civil Engineer and Licensed Surveyor of Kirsten Hall, Lagos, subject to your Honour's approval, or in the alternative, Mr. J. Bagan Benjamin, Civil Engineer and Licensed Surveyor."

His Honour Lt-Col. Moorhouse, C.M.G., D.S.O., promptly replied on the same date as follows :—

"By all means bring Mr. Macaulay on Wednesday morning. My object in confining my original invitation to the Members of the Legislative Council, the elected Members of the Town Council, and the members of the local Press, and asking each of them to bring another gentleman, was prompted partly by want of space and partly because I felt that those invited would be in a better position to say who were most keenly interested in the scheme than I could possibly be myself.

I should be glad to see Mr. Benjamin, and if he is no nominated by anyone else, please bring him also."

---

## IROHIN ILE ẸJỌ

[ Lati ọwọ ATOLUGBOKUN. ]

### "OLOTỌ KO NI KU—SI IPO IKA"

Idajọ tabi *Judgment*

Ni ijọ keje oṣu yi ni ijọ Alaruba (*Wednesday*) ni Adajọ Ọlọla Sir Fredrick Alan Vander Meulen ka idajọ rẹ nipa ẹjọ ti Frank Macaulay ọmọ Ọgbẹni wa Herbert Macaulay, Kinnun, Onibudo pe Abudu Kadiri, Dawodu Seriki ati Sule Abasi Seriki (Suit No. 202/24) wipe on ya wọn ni igba poun (£200) gẹgẹ bi iwe ti wọn ṣe fun on nigbana. Frank Macaulay gba Lọya Ọlayinka Alakija, Ọgbẹni Montacute Thompson ṣe iranlọwọ ninu ẹjọ na, awọn ti Franki pe lẹjọ gba Lọya Latunde Johnson. Ẹjọ yi bẹrẹ, awọn ẹlẹgiri ni toto ni awọn fi ọwọ si iwe ṣugbọn Franki ko fun awọn lowo ko to gba ilẹ Hausa lọ, otọ ni Franki mu awọn lọ si ọdọ ọrẹ rẹ Abram Willoughby ẹniti ọṣẹ iwe na. Ọgbẹni Lọya Latunde Johnson sa gbogbo agbara rẹ tobẹ to fi sọ fun Adajọ pe asiko ti Franki ni on ya wọn ni owo na ni Ijọba ba ro ẹjọ ti wọn si gba Irinwo poun lọwọ rẹ (£400) ọsẹ to tẹ le ni Franki ni on ya wọn ni igba poun (£200) ṣugbọn gbogbo agbara awọn ẹlẹjọ yi pa bo ni, nitori aki ṣe ore, ka ri ibi ni idi rẹ.

Lọya Alakija fi han Adajọ pe nigbati owo Motọ Franki ṣi nkẹriri ni asiko ti o ya wọn lowo yi ẹgbẹdọgbọn poun ko da ni idi gba, ka to ṣẹṣẹ wipe Ijọba gba irinwo poun lọwọ rẹ igba ko ṣa lọ bi orere, Franki papa sọ wipe on ko kuro ni kọtu ki on to san irinwo poun ti Lọya Johnson nfun ika mọ ati pe nigbana *Motor Car* ti on nta, o nwa lati ilu Oyinbo bi igba alubọsa nde lati Kano ati pe owo *Motor* yi npe on. O si fi risiti (*receipt*) han ti akibọ Ogunbiyi fi fun on ni owo iwe Banki fun ẹgbẹta poun (*£600 Bank Counterfoil*) ati oriṣiriṣi risiti ati iwe owo, eviti ko ti lẹ ti pe ẹjọ fun, fun awọn to ṣanu fun bi awọn ati ore ṣegi enia wọn yi. Ọga ni Vander Meulen ẹniti o fi ate fun Franki fun Igba poun ati poun mẹrindilọgbọn pẹlu ṣile marun owo irin ẹṣẹ. Ninu ẹjọ yi ni obinrin kan Beatrice fi wọ ẹwọn ijọ mẹrinla. Franki eyi to kọ ẹ ni ọgbọn, bi enia jẹ ọ lowo, ti asiko to da ba ti to, pe ni ẹjọ ko gba Idajọ sọwọ na, ki iwe

owo to gbọkanle ko ma di ofifo mọ ẹlọwọ. Franki oku orire.

### "INTERPLEADER"

Ni ọjọ *Wednesday* ijọ keje oṣu yi ni iwaju Ọlọla Vander Meulen ni ẹjọ yi wa si iwaju ile ẹjọ, Salami Gata *Versus* Samuel Bamgbose Joseph Ọkanlawọn Balogun *re* Ẹbun Balogun *Claimant*—Ọgbẹni A. Kayọde lowa fun Salami Gata Ọgbẹni Olayinmika Alakija lo wa fun Ẹbun Balogun ẹniti o sọ wipe on lo ni ẹru ti Salami Gata gba iwe aṣẹ si lati ko ta. Ẹbun Balogun aya Ọkanlawọn Balogun lo jẹ obinrin yi ṣe bi Okunrin o sọ fun Adajọ pe ẹru ti wọn ń diresi ile ti on ni nigbati on fẹ gbe arede ni wọn fi wọn ta on lọrẹ *Motor Car* yẹn L.363 ọwọ Mrs Benjamin ni on ra, o san owo diẹ silẹ, awọn aga ati Jigi owo onigbanjo Gladstone Ọṣun ni on ra, obinrin yi pe Lọya Wilson to ṣe risiti fun on nigbati on ra *Motor Car* wa jẹri o si pe Gladstone Ọṣun wa jẹri gbogbo wọn sọ bakanna, ṣugbọn Lọya Kayọde fẹ da Ẹbun Balogun ni agbo nu, gbogbo rẹ ẹhin igba loyin igbado si. Ọga ni Lọya Ọlayinka Alakija pẹlu ara rẹ ti ko le to kẹra wa, ofi oro na ye Adajọ finifini. Adajọ si gba fun. Oni ki Salami Gata ẹniti awọn ẹlẹgiri ẹbọra wọnyi jẹ lowo ko san poonwun marun ṣile marun owo irin ẹsẹ fun Ẹbun Balogun, bi enia ko to ila de ki de ko ma ru mọ loju. "*Owe la gba.*"

### POLICE CASES

#### "ẸMU PA ẸLẸ MU"

Ọrọ yi lo yo siwa, nipa irohin ta fun nyin laipẹ yi wipe Baba ati ọmọ rẹ ti oruko wọn njẹ Sanmẹnu Giwa ati Oseni Arole ti Okepopo ni Eko wipe wọn ji Ọgbẹni J. A. Labinjoh ti ita Faji ni Raketi ati iṣana Bisiko, ni ijọ keje oṣu yi ni ẹjọ yi wa siwaju Adajọ Ọgbẹni H. S. Berkley ṣugbọn nigbati Ijọba ko ri Labinjọ ẹniti o fi ẹsun olesun awọn Ọgbẹni wọnyi. Adajọ ni ki wọn ma lọ, ijọ to ba ya Labinjọ ko wa ro ẹjọ rẹ. Lọya Baptist ni awọn Ọgbẹni yi gba.

Ni ijọ kan na yi ni awọn Ọlọpa ba awọn Kurumọ meji ro ẹjọ Ekini James Okonu Ekeji John Bassey wipe wọn ji Iya alin Caroline Johnson "Araoti" ni gele ṣẹda ọpa mẹrin. Awọn odaran ba Lọya Thompson. Ki ṣe nilọloyi ni ọran na. Kan nnu awọn Kurumọ yi ọwọ Ijọba tẹ ni oṣu December, ijọ kẹrinlelogun oṣu na wọn ju ẹjọ si ẹwọn oṣu mẹfa on lọ sọ wipe John Okonu lo ba on lọ si ṣabu Iyafin yi nigbati wọn bẹ wọn ba Adukẹ ni ṣabu nwọn nyọ owo ẹja bẹ ni John Okonu gbe mu aṣọ ṣẹda lo gbe lọ, on wa tiri wọn ko ri; iṣẹ ni Ijọba gbe gbe on sẹwọn, Obinrin kan ṣẹkiri oruko rẹ njẹ Caroline ni John Okonu lo ta aṣọ ṣẹda yi fun on, aṣọ yi Ijọba si gba lọwọ Caroline yi. Adajọ da John Bassey silẹ nitori pe ẹjọ ko kan. Adajọ fi ẹjọ si *Friday* ijọ kẹsan oṣu yi. Ni ijọ Jimọ na ni Adajọ da ṣẹria fun John Okonu wipe ko lọ ṣẹwọn oṣu mejila pẹlu iṣẹ aṣegan. Ni ijọ *Monday* ijọ kejila oṣu yi Ijọba tun mu John Okonu wa si ile ẹjọ fun ẹsun ole, Lọya Thompson ko le wa ṣugbọn Ọgbẹni Dekunle Wright lo ba ṣe ẹjọ yi wọn ko fa gun lọ titi, Lọya ni awọn jẹbi, Lọya Wright si bẹ Adajọ, Adajọ ni ko ṣe oṣu mẹta si ṣugbọn ko dapọ mọ oṣu mejila (*3 months imprisonment to run concurently.*)

Ni ijọ kejila oṣu yi ni ijọ *Monday* ni ẹjọ ti Town Council pe D. Gladstone Ọṣun wipe ko tẹle ofin ki kole, ṣugbọn Gladstone Ọṣun ko le wa jẹ ẹjọ, nitori ẹjọ rẹ kan wa niwaju Adajọ Vander Meulen ṣugbọn Adajọ ko ma gbọ iyẹn o. Oni ki Ọṣun san ogun ṣile ko si tẹle ofin ti Munisiba fun, ko ṣe gẹgẹ bi nwọn ti wi larin oṣu kan loni.

Emi ni tinyin nitoto,

ATOLUGBOKUN.

---

## IN MEMORIAM.

In loving and affectionate memory of our dearly beloved brother, father and uncle.

EPHRAIM MARMADUKE OLUFẸSOBI BRIGHT,

*Merchant. Patriot. Gentleman.*

Who quitted this vale of tears for the Mansion of the Blest, at Ode Ondo, on the 10th January 1907

"Well done thou good and faithful Servant, enter into the Joy of thy Lord"

(Mrs.) Marian Adefunke George
Adeoye Deniga
D. Ayodele Bright
(Mrs.) Caroline Taiwo Adegun
Olutele Bright
(Mrs.) Charlotte Olatisayo Moussah
Olugboyega Bright
Miss Sola Bright
Master Ebun Bright
John Tade Bright
Etc., Etc., Etc.

---


## MUSIC LOVERS.

Now in stock limited quantity of latest dance Records :—Fox-Trots, etc.
Sacred Songs for Christmas, etc.
Gramophone Main Springs, and other spare parts.
Also in stock, finest quality Guitar light touch melodious tones, fitted with engrave aluminium Tale Pieces; specially constructed for any tropics.
Guitar, Violin, Mandolin, Banjo Strings, and other accessories in stock. Call at Vidal R. Cole.

109 & 111, Broad Street
"AJENIFUJA" Store.
Lagos Nigeria.
P. O. Box 201.

## *This, That, and The Other.*

*By an Old Crow.*

### Eko Akete's First Annual Dinner at Bonanza Hotel.

**J. H. DOHERTY ESQ., PRINCIPAL GUEST.**

Thursday the 9th inst. will go down in history as a Red Letter Day in the annals of the journalistic world of Nigeria; for it was the evening of that day that the First Annual Dinner of this paper took place in the Bonanza Hotel—the ocassion standing as a record-breaker being the first annual dinner ever held by any Newspaper in Nigeria.

Promptly at 8.30 p.m ticket holders began to file in the precincts of the great hotel and at about 9 o'clock there was quite a fairly large gathering. A few minutes after a lady and the gentlemen present had taken their seats the news that Mr. J. H. Doherty, the Principal Guest for the evening, would be unable to attend owing to a bereavement that afternoon was received with sympathy. Messrs. Duro Thomas and L. O. Thompson (Dispenser) were elected Chairman and Sub-Chairman respectively. At 9.5 the proceedings of the evening were opened by the Rev. A. A. Puddicumbe who said the grace.

The Chirman's Opening Speech followed. It is regrettable that owing to a Concert which was going on at the first floor and other meetings at the adjoining apartments of the hotel, the playing on the piano, and gramophone, not to say anything of the intermittent shouts of applause, interfeared a great deal with the facility of hearing and recording the various speeches of the evening.

The Chairman, in his opening speech paid a glowing tribute to the Editor of *Eko Akete* and referred to the gathering of that evening as unique in Nigeria journalistic history.

This was followed by Refreshments. After travelling through the items of the Menu (all credit to Mr. Rahm the Manager of the hotel) the toast of the King was heartily drunk to.

The toast of The West African Press was ably proposed by Mr. Oluyele Bright. The efforts of our journalists, he thought, are not receiving due appreciation from the public to whose interest and welfare these efforts are directed. The *Eko Akete*, he is sure, is being read by more than two thousand people weekly. To-night looking round him he found not more than 30 people. Where are the remaining 1,970 readers? This toast was responded to by Mr. L. O. Thompson who supported the sentiments expressed by Mr. Bright.

The toast of the Editor *Eko Akete* was next proposed by Mr. B. Ade Mumuney. He became acquainted with Mr. Adeoye Deniga, popularly called "The Professor" on account of his numerous literary productions, as recently as 8 years ago (laughter). Mr. Deniga's first editorial effort dated as far back as 1909 when he started *The Lagos Astrological Mercury*—a paper hand-written and read by a small circle of people. In 1910 he edited *The New Age Herald*; in 1913, *The Herald-Alore*—a bilingual and to-day we have the *Eko Akete* at the instance of which we are all assembled here this evening.

In religious circles he is as active as in the journalistic field—This is borne out by the fact that he occupies no less an office in his Church than that of the Superintendent of the Lagos Mission (hear, hear).

The toast was responded to by Professor A. Deniga the Editor of this paper. He is very thankful to Mr. Mumuney for the high compliments paid him. Whatever he has been able to do in his little way has been done through the selfless assistance of the various contributors to the paper. A paper without a qualified staff of writers will go to the dogs, and he thanked God he is able to boast of first class writers. He thanked all those present for sparing the time to come and participate in the function of the evening. It is an honour done to him—it is an honour done not only to him but to the country—nay, it is an honour done not only to the country but the whole Negro race—(applause).

This was followed by the Chairman's closing speech. He appealed to all those present to put their good wishes to practice—i.e.— to subscribe to the *Eko Akete* which is already having the largest circulation of all the local periodicals and also to induce their friends to do so.

Among those present were Messrs Olufemi Blaize, A. Tanimowo Ariori, D. Ayo Bright, J. T. Bright, S. A. Johnson, Alfred Williams, N. A. Soluade, A. F. Breck Akibogun, Miss Ebun Williams, and a host of others.

The proceedings were brought to a close with the singing of God Save The King!!!

AN OLD CROW.

### OUR BOOK TABLE.

Dada Adesigbin's Calenda for 1925 containing *inter alia* the life size photograph of our respected deceased townsman James Wilson Vaughan, Merchant, Mystic, Philanthropist.

**EKO AKETE.**

EKO, SATURDAY, JAN. 17, 1925.

## T'OYINBO BA MA LỌ, "A ṢU S'AGA."

A tọrọ gafara lọwọ ẹnyin ọkawe wa fun ede ti o dabi o ku diẹ ki o to ti a pe yi, ṣugbọn ti ẹnyin na ba tun daro lọna keji, ẹ o ri kedere pe owe ti a ma nsaba pa ni nigbakugba ti a ba ri pe ẹnikan ba fẹ fi iwa àjà-nporò alẹ lọ ni ninu ohunkohun ti irufẹ iwa bẹ̀ ko ṣẽ gbà, ti kò si sẽ kọ̀, lo mu irufẹ owe yi wa.

Kodede ti a fi mu owe yi wa si iranti nyin, nitori ṣàṣà enia ni ko mọ pe gudugbẹ̀ kan já ni ijarun, ninu akanṣe ipade ti Ijọba pe t'ọtun t'osi diẹ ninu awọn aṣaju ilu si ni'le Ọgagun Moorhouse fun ati bojuto imura ti a nnu nisinsinyi fun gbigba Arẹmọ Ọba, ẹniti yio fi ẹsẹ ọla rẹ tẹ ilẹ yi ni ãrọ ọjọ kẹrinla oṣu *April* ọdunni t'ọwọ t'ẹsẹ.

A gbọ pe ninu Ipade na Igbakẹta Ọba, eyini ni Ọgagun H. C. Moorhouse Oloye D.S.O., C.M.G., daba ki awọn ti o mbẹ ninu ipade na fi Dokita Randle ṣe Alakoso tabi Alaga iru Igbimọ *(Committee)* ti nṣe ipalẹmọ yi; lai ṣẹ̀ṣẹ̀ tun ma sọ ni asọtunsọ, àbá yi run ẹnikẹni ninu; ki ṣe pe H. C. Moorhouse Ọgagun ko to l'ẹnu didaba bẹ̀, ki iṣe pe Ọgbẹni Dokita Randle ti a mu orukọ rẹ wa si ipade na (on papa wa nibẹ) lati jẹ Alaga Igbimọ Ilu na, ko tọ, ko si yẹ, ani ki iṣe pe awọn enia na ti nwọn jẹ Aṣoju Ilu, gbe agbéré pe Ọgbẹni na ko to ṣe olori wọn lo ṣe jẹ ki ọrọ na rí ẹnikẹni ti o gbọ ọ lara, bi igbati ẹrú *(slave)* ẹni fi ọwọ gbe aya ẹni l'ọmu, bikoṣepe ipo àgbà òṣikà ti a woye pe Ọgagun ti o damọran yi fẹ fi ara rẹ si nipa dida họwu, họwu silẹ, nigbati o mọ pe o k'eni k'ọla ti on fẹ lọ si'le fun itọju ara rẹ, nitori eyi ti a gbọ pe o ti itori rẹ lọ sile—ara lile sa ni ipẹkun ọrọ; kini iwa họwu họwu na ti a ntọka si? Dajudaju Ọgbẹni *Lieut Governor* Moorhouse ko ṣ'alai mọ pe bi igba ọrẹ ologbo ati ekute ni t'ọtun t'osi awọn ti o wa ni ipade na ri si ara wọn; ẹnyin mọ irẹpọ ti o wa larin ẹtu ati ina?

Nigbati Ọgbẹni Ọgagun na mọ eyi, o ṣe dábà irufẹ eyiti o da yẹn? Loju wa ohun ti iba ṣe ti iba yẹ yẹ ni pe ki o ni bi on ti nfẹ lọ si'le yi, on mọ ede aiyede ti o wa larin ẹnyin Bọkinni wọnyi lati iwọn ọjọ gbọrọ wa, ṣugbọn ohun ti o de lọ yi ki iṣe ohun ti a le ti ori gbún-gbùn-gbún ti o mbẹ larin nyin fa ina rẹ sẹhin, nitorina laini ifẹ tabi ifura ẹnikẹni pe on pọ̀n si apa ọtun tabi apa osi *(without the least desire to side with the predilections of either party—the Exclusives and the Democrats)* nitorina on da ni imọran pe ki Ọgbẹni W. Birrell Gray Ọgagun, ti o jẹ Balẹ Ilu Eko nisinsinyi jẹ Alaga iru Igbimọ bẹ̀; lalai jẹ pe a gba ẹiyẹ ajẹ, tayọtayọ ni ẹnikẹni yio fi gba imọran Ọgbẹni yi; ṣe nigbana Ọgbẹni Birrel Gray Balẹ Ilu, iba mọ ọgbọn ti yio fi ko t'ọtun t'osi jọ, ti "pẹkẹ ko si ni mì" titi ọjọ ajọyọ na yio fi de. Dokita Randle ko tẹ wa l'ọmọ pa, jare, ẹ ma ṣì wá gbọ́ o: orisirisi àgbà ni mbẹ, àgbà ilẹkun mbẹ ti ko ni ọgbọn ti ara rẹ, bikoṣepe ki a ma ti s'ihin ti s'ọhun àgbà gbà-ngbà mbẹ ti o kàn dágbà lasan lai ni ọgbọn ọmọ àna ni ọpọlọ *(brain)*; àgbà ṣákála si mbẹ àgbà jaun—ani ṣe bi àgbà onilãkàyè kan ba mọ pe ede aiyede kan mbẹ larin A., B., ati D., kàkà ki o tubọ mã ṣúná si ede yi, yio du ki on jẹ ẹniti yio wa l'agbedemeji awọn A., B., ati D., lati tun nkan ṣe; ko ni gb'oju gb'aiya dábà pe ki A. jẹ gaba kan lori B. ati D., bẹ̀ si ni ko ni jẹ ki D tẹ A ati B ni bãfin ṣiṣe olori tabi alakoso ara wọn; bi ọrọ ilu da awọn mẹtẹta pọ, bi alagba na ko ba ni le ṣe irufẹ akoso bẹ, yio pe alagba miran ti ko ba t'ọtun t'osi ni muradi gbọn'mi si omi ko to wọn, ẹ o si ri pe ko ni ṣai ṣe ẹnikẹni lõre ti a ba mu irufẹ ọna bayi pọn.

Bi a ti nkọ iwe yi, Ọgagun Moorhouse yio ti ma lọ rẹrẹ si Ilu Oyinbo ni agbakun, ṣugbọn a tanma pe yio ti tẹ gãsi imọran onikumọ ti o da na bọ awọ *(leather)*

bibẹkọ, owe ti a fi bẹrẹ kikọ iwe yi le di àmì abawọn si lara.

Agba ọ̀ṣìkà k'amari lo ju !
Kamari ! !

## Open Letters.

TO CELEBRITIES, NOTORITIES, ETC., IN DIFFERENT WALKS OF LIFF

**No. 50.**

To
DR. JOHN RANDLE, M.B., CH.B, *(Edin.)*
31, Marina
Lagos.

Veteran Doc,

So your Committee have found it necessary to thwart the efforts of the Hons. The First and The Second Lagos Member, and those of Mr. B. C. Vaughan in the praiseworthy and laudable attempt to bridge the gulf of misunderstanding which unfortunately exists between your Committee and a prominent member of this community, by the former's blank refusal to meet with this particular member, that is to say, Mr. Herbert Macaulay C.E. in order to find a *modus vivendi* by which to work hand-in-hand in the country's interest, particularly at a time such as this, when steps are being vigorously taken to present a united front in giving The Ambassador of The Empire, a right royal welcome on his advent to these shores in April next.

Again, at a meeting held as recently as on Saturday last at the Glover Memorial Hall, in your reply to a question put by one of your party that is, Mr. J. Akiyemi Oshodi, *anent* the above affair, you are reported to have said that why objection was taken to Mr. Herbert Macaulay's name being eventually included in the prospective Coalition Committee, is that that gentleman is a permanent foe of the Government—whatever this may mean ! But you will doubtless agree with me on your reading the extract from a letter sent as a reply by no less a personage than His Honour the Lieut-Governor (S.P.) to The Hon. J. Egerton Shyngle published elsewhere in this issue, that that reply GIVES A DIRECT LIE to your ejaculatory remarks—Shame ! ! to borrow a biblical terminology, would your committee curse whom the Lord does not curse ? *Allons donc* !

It is to me a matter of regret to observe that consciously or unconsciously, some members of your committee are actually living up to the tradition of the unenviable epithet fastened on their necks, Goodness knows who ? Indeed one of your members at one time in The Honourable Board of our Legislative Council had the brazen effrontery to inform the "House" in one of its sittings that he is glad to be one of the "*Contemptibles*" or words to that effect.

On the face of this shameless admission, is it any wonder to see that the community has scant regard, if any at all, for the members of your committee of such frame of mind.

Again, did any Secretary of State for the Colonies at any time have occasion to inflict so pitiless a lashing on Mr. Herbert Macaulay the seeming *bete noire* of your party, against any future attempt in forwarding that august, personality at 10, Downing Street, a Telegram or Petition which, in the opinion of that functionary, is nothing short of a "scarcely veiled threat of seditious agitation" as was certainly the case with one of your number some years ago.

In fine, it will be worth your committee's while, in future before showing their apparent cloven hoof in any public movement, always to ponder over this great truth as enunciated by that prince of English Statesmen, EDMUND BURKE "A great Empire and little minds go ill together".

Think and consider ! Think and consider ! !

*Au revoir.*

EKO AKETE

---

## A-SỌ-TẸLẸ L'O NJẸ ỌRỌ ANA !

*(Part II.)*

[ *Lati ọwọ* ATARI-AJANAKU. ]

Si Oni'we-irohin "EKO AKETE."

Mo bẹrẹ f' oji,

A ro wipe gbogbo ẹnyin ti ẹ ka Wosika wa ti ọsẹ ti o kọja ni gbogbo ọrọ ti a sọ nibẹ nipasẹ *Codicil* tabi Iwe Ipingun -keji ti Ọgbẹni James George ni on ṣe fun Ologbe Andrew Wilkinson Thomas, Oni-gbanjo, yé yeke-yeke ; nitorina, die yoku nipa ọrọ kanna yi, ni a o tun sọ ni ọsẹ yi.

Nigbati awọn ẹbí Anduru jade oku tan, ti nwọn ka Wili, ti nwọn tun ka *Codicil* pẹlu, ariwo ta.

Ninu *Codicil*, ki a sa kúku wipe, gbogbo Ohun ini Anduru, Ile, Ọna, Motọ, ati Owo bi ẹgbẹrun pọnwun ọna mẹwa (£10,000) ọmọ kanṣọṣọ—Mrs. Christiana Ayọ Coker—ni a ko gbogbo rẹ fun. Ohun abami miran ti o tun wa ninu *Codicil* na ni wipe, Alufa Evan Williams, B.A., ti Ṣọṣi Olowogbowo, ẹniti o nṣe ẹbí Ologbe, ti o si jẹ ọkan ninu Baba Isinku (*Executor*) ninu Wili, James George ni Andrew Thomas sọ wipe ki on ha`orukọ rẹ kuro nibẹ, ki on si fi ti Alufa T. A. J. Ogunbiyi ti Ṣọṣi Breadfruit dipo rẹ.

Eyiti a nwi yi pẹ ju, gbún-gbùn-gbún ti de si arin awọn ọmọ Ologbe ; l'aifa a gun lọ titi, meji ninu wọn, Mrs. Comfort Agbe, ati ọbakan rẹ ọmọ kekere kan, Adenikẹ, pe James George, Alufa Ogunbiyi ati Mrs. Ayọ Coker l'ẹjọ wipe ki Kotu jọwọ ba wọn sọ *Codicil* di oku, nitoripe, li akoko ti nwọn sọ wipe Baba wọn Ologbe ṣe *Codicil* na ailera ko jẹ ki o ṣe e.

Ọlọla Lọya Eric. O. Moore, Lọya E. J. Alex Taylor, Lọya Irving (Oyinbo) ati Lọya Adebayọ Doherty ni o wà fun awọn ẹlẹjọ : Ọlọla Kitoyi Ajasa ati Lọya Mobọlaji Akinṣemọyin wà fun apakeji.

Ẹrí ti Dr. Gray (Oyinbo) ati eyiti Dr. Aitkin (Oyinbo) ekeji rẹ jẹ fihan gbangba wipe Anduru ko le ṣe *Codicil* ti James George sọ wipe on ṣe fun u ni ọjọ kejidi-logun oṣu *September*. Dr. Aitkin ni ẹnikẹni ko yin i si on l'eti fẹrẹn wipe Anduru fẹ ṣe *Codicil* tabi Iwe Ipingun ; bi bẹ kọ, on iba sọ fun wa wipe ko le ṣe ohunkohun ti o njẹ bẹ li akoko na, nitori gbogbo làkaye ori rẹ ti daru.

Mrs. Comfort Agbẹ, ọkan ninu ọmọ oloku ati ẹniti o pejọ, jẹri wipe, otitọ ni aisan ra baba on n'iyc li akoko na, orun ṣà ni o nsùn, ati wipe; ni ọjọ kejidi-logun oṣu *September, 1923* gan ti nwọn sọ wipe o bẹ wọn ni *Codicil* ṣe yi, ọjọ na gan ni o fi aṣọ lasan bò ara, ti o si wipe on fẹ bata lati wọ lọ si ibi Idibo (*Election.*) bẹni ẹsẹ rẹ mejeji ni o wú!

Lọya Ajasa, alagbaso apakeji bere lọwọ Mrs. Agbe, bi o mọ, tabi ko mọ wipe, ẹniti o le ni baba rẹ (*a strict father;*) eyini ni Baba ti ko jẹ gba igbakugba fun ọmọ kan: Comfort si dahun wipe, Bẹni! Awa ko mọ kini Ajasa ri, ki o to bere iru ọrọ bayi, nitoripe, gẹgẹ bi awa ti mọ Ologbe Anduru si, ko nṣe Baba ti ki ngba igbakugba, ani, a tilẹ fẹrẹ le fun u ni súna "A-kẹ-jù" ti o nba ọmọ rere jẹ.

Lẹhin ti Mrs. Agbe sọrọ buṣe, Samuel Adeyẹmi Clay, ọkan ninu awọn ti o fi ọwọ si *Codicil*, bọ si ori Atẹ. O si wipe, ni ọjọ kọkandi-logun oṣu *September*, 1923, ti nwọn sọ wipe ki on fi ọwọ si *Codicil* Anduru gẹgẹ bi ẹlẹri, on fi ọwọ si i; ṣugbọn ni gbogbo akoko na, Anduru ko wu'ko, ko ha kẹlẹbẹ; ko le sọ ohunkohun, bọ-bọ ni agutan nwo!

Mr. Jaiyẹọla Agbe, ọkọ Comfort jẹri wipe nigbati on lọ ki Anduru baba iyawo on ni ọjọ kẹtadi-logun oṣu *September*, ko mọ on daradara mọ, nitori lākaye ti da opolọ rẹ rú. Nigbati Ayo Coker, ọmọ rẹ si wa si iyara, isokuso ati ọrọ odi ti Baba rẹ nsọ da a lamu pupọ, papa, nigbati o ni ki o lọ ko awọn Wosika (*Letters*) wọnyẹn wa, ki o fi ọkan ranṣẹ si Mr. Carr, okan si Mr. Kufeji, okan si Ile Oba (*Government House.*) Jaiyeọla Agbe tun sọ gẹgẹ bi Alufa Evan Williams, ẹniti ko mọ wipe nwọn ti fi ọbẹ ẹhin jẹ on ni'ṣu, ti ṣe ājo Anduru to li ọjọ na, ti o si fi onjẹ nù u; ati bi Dr. Obasi ti wipe on yio kọ orin "Awa nyin Ọ, Ọlorun," ki on to jade ninu yara Anduru. Ni ọjọ kejidi-logun ati ọjọ kọkandi-logun oṣu *September*, ati fun ọpọlọpọ ọjọ lẹhinna, ọrọ Anduru ko ba ti araiye mu, o si daju wipe ko le ṣe *Codicil* ti nwọn sọ wipe o ṣe yi li akoko na.

Alufa Evan Williams jẹri wipe ibatan on ni Anduru nṣe, nwọn si ranṣẹ pe on ni ọjọ kẹtala oṣu *September*, nigbati "ọrọ lu." Lati igbana, titi di ogun'jọ oṣu *September*, 1923, firifiri ni on nlọ sibẹ, o si ni iye igba ti on nfi onjẹ nu u, nitori ko le da jẹun fun ara rẹ. O daju wipe ko le ṣe ohunkohun ni akoko ti nwọn sọ wipe o ṣe *Codicil*. O ni on mọ Alufa Ogunbiyi daradara, ṣugbọn on ko mọ ọ ni ọrẹ Anduru titi Ologbe na fi ku.

Mr. J. A. Faṣanu jẹri wipe, ọrẹ Anduru ni on nṣe, ojojumo ni on si nlọ sibẹ ni oṣu *September*, papa, lẹhin ti "ọrọ ti lu" tan. Ni gbogbo akoko yi, orun ṣa ni o nsun nitori ailera. Faṣanu ni on wa ni 'yara Anduru ni ọjọ kejidi-logun oṣu *September*, ki awọn James George to de, nigbati Alufa Ogunbiyi lé on pẹlu awọn ẹlomiran jade kuro ni 'yara. Werewere ni Anduru nṣe nigbana, o si nfẹ gbidanwo lati bẹ silẹ lati oju ferese Ile-pẹtẹsi rẹ.

Mr. J. Ọmọṣalewa Thomas jẹri wipe ọmọ Anduru ni on nṣe, ati wipe ọdọ rẹ ni on wa li akoko ti "ọrọ lu." Fun ọdidi ọsẹ meji tabi ju bẹ lọ, on ko ri àye lọ si ibi iṣẹ rara, nitori aisan baba on. Fun ọjọ pupọ lẹhin ti "ọrọ lu," isọrọ ati ihuwasi rẹ yatọ patapata si ti araiye. Ni ọjọ kejidi-logun oṣu *September*, 1923, Alufa Ogunbiyi wa si ile baba on, o si wipe on nreti James George ẹniti o de lẹhinna. Nigbati awọn ẹlegiri mejeji wọ 'yara, nwọn ba on ati awọn ẹlomiran nibẹ. Alufa Ogunbiyi si sọ wipe ki gbogbo wọn jade ni 'yara. On kọkọ fi àké kọ 'ri, ṣugbọn nigbati Alufa Ogunbiyi fi ori po on lọwọ titi, on jade. Iṣẹju melo kan si i lẹhinna, awọn mejeji jade, nwọn ni awọn ko le ṣe ohun kan gunmọ, nitori ōrun nda baba on lāmu pupọ. Ni ọjọ keji, nwọn tun de, nwọn tun le wọn jade kuro ni 'yara, lẹhinna ni James George ni ki on ke si ara ode meji wa fun ẹlẹri. On pe Samuel Clay. James George pe A. O. Thomas, awọn mejeji wọ 'yara, on ko mọ iru Iwe wo ni nwọn fi ọwọ si, ṣugbọn o da on loju wipe, ti o ba jẹ Iwe-aramu kan, Kōtu yio sọ ọ di oku.

Lẹhin ti awọn ẹlẹjọ ro ẹjọ tan bayi, awọn apakeji bọ si ori atẹ.

Mr. James George, *Solicitor*, bura o si wipe, on ti nṣe iṣẹ *Solicitor* lati ọdun gbọrọ, ọrẹ timọ-timọ Andrew Thomas ni on si nṣe. On mọ Wili tabi Iwe Ipinzin ologun ṣe pupọ. Anduru bẹ on ni Wili kan ṣe ni ọjọ kẹtadi-logun oṣu *July, 1923*, on si ṣe e. Nwọn ranṣẹ si on ni ọjọ kẹtala oṣu *September, 1923*, wipe "Ọrọ" lu Anduru, on si lọ wo o ni ọjọ kanna tabi ọjọ keji. Ni ọjọ kejidi-logun oṣu *September* kanna yi, o ni Anduru ran Awa-motọ rẹ wa pe on, oju rẹ si wa nilẹ daradara nigbati on de ibẹ, on si ba Alufa Ogunbiyi ati awọn ẹlomiran ni 'yara li ọdọ rẹ nigbana. Anduru ni ki gbogbo enia ti o wa ni 'yara li ọdọ on jade, bi gbogbo wọn si ti njade lọ pẹlu Ogunbiyi, bẹni o ju ọwọ si Ogunbiyi wipe ki o duro; ni oju Ogunbiyi na ni o si ṣe sọ wipe on fẹ ṣe *Codicil*, ati wipe on ko si fẹ Afa Evan Williams B.A. ni Baba Isinku ati Olutọju ogun on mọ, Afa Ogunbiyi L.Th ni on fẹ fi rọpo rẹ. O si ni gbogbo Dukia ti on ti fun mẹfa ninu awọn ọmọ on tẹlẹ ri ninu Wili ti on ṣe fun u ni oṣu keji ati Ile, Oko, Owo, Motọ ati nkan iyebiye miran, ọmọ kanṣoṣo eyini ni Ayo Coker ni on tun fẹ ko gbogbo rẹ fun ninu *Codicial*, ati pe Ile nla ti on ngbe ni Anikantamọ, pẹlu gbogbo ohun ọṣọ (*Furniture*) inu rẹ, ti on fi ṣe Ile ẹbi (*Family House*) ninu Wili, ki nwọn ko gbogbo ohun ọṣọ (*Furniture*) inu rẹ ati aga, ibusun, ji... agogo, *Carpet* ati gbogbo ẹni ti on tẹ silẹ nibẹ, ati gbogbo nkan ti o wa ninu ile na pẹlu awọn ... ran ti a fi kọ, ki nwọn ko gbogbo rẹ fun Ayo ... on yi nikanṣoṣo pẹlu, ki nwọn si tun gbogbo ... ihobo fun awọn ẹbi ati awọn ọmọ on ...

James George ni on kọ gbogbo rẹ si takada, Afa Ogunbiyi lo si ya on ni gege (*pen*) ti on fi kọ ọ. Nigbati on de'le on tẹ (*type*) gbogbo rẹ sinu iwe, on lọ s'ile Anduru nijọ keji, on tun ba Ogunbiyi iti awọn ẹlomiran nibẹ. Anduru si le gbogbo wọn jade, a fi on pẹlu Ogunbiyi nikan loku. Lẹhinna, on fun u ni iwe *Codicil*, nigba'i kọ si le a daradara, to nwa jigi oju (*Spectacle*) rẹ, l'ogan, Afa Ogunbiyi ti wa ni awakan n'iyara, o si mu u un Anduru. On James ka gbogbo ọrọ to wa inu *Codicil* s'oke, lẹhinna on ni ki nwọn pe ẹleri mẹta wa, Mrs. Mokolu, Mr. A. O. Thomas ati Mr. ...ay si je ipe na. On si je ki Anduru fi ọwọ si ...e na l'oju wọn, ki awọn papa to t' ọwọ bọ ọ.

Loya E. J. Alex Taylor to ra ni ẹgba okẹ nijọ yi, ...igbati o na 'wọ gan Mr. James George, o jẹ ki ...kọ bi akoko, nṣe lo nlagun bọyọ ninu apoti to ...yọ idiko fara l' apo fi nu oju. Nigbati on ro ...ọ, o ni on ka nkan to wa ninu *Codicil* na s' oke ...n Anduru ni, ṣugbọn nigbati Loya Taylor bere ...wọ rẹ, o ni on ka a soke ki Afa Ogunbiyi ba ...mọ nkan ti on kọ sinu rẹ ni. O ni on ko ...re lọwọ Dr. Aitkin tabi Dr. Obasa bi lakaye ...nduru pe to lati ṣe *Codicil* lakoko na tabi ko pe, ...ni on ko si bere kilo ṣe ti Anduru fẹ gbe ...egbo nkan tamutamu ti o ti fun ọmọ mẹfa ...a owo bi ẹgberun ponun ọna mẹwa £10,000 ...ọmọ kan ṣoṣo. O si wipe Afa Ogunbiyi ti ...a ponwun mẹrindiladorin, ṣile mẹtala ati kọbọ ...rin £66-13-4 ti *Codicil* yọda fun u.

Mr. A. O. Thomas jẹri pe ọrẹ Anduru ni on ..., on si ranti ojo ti "Ọrọ" lu u; on tun ranti ... Afa Ogunbiyi ati Mr. James George wa sile ...duru ni ọjọ kejidilogun oṣu September, 1923. ...unbiyi lo kọkọ de, lẹhinna James George, ...unbiyi si le awọn jade kuro niyara. Nijọ ... nwọn tun de nwọn tun le wọn jade, lẹhinna ...es George tun kesi on lati f' ọwọ si *Codicil* ...ẹri, on si fi owo si i, lẹhin ti ologbe papa ...wọ si i tan pẹlu inira pupọ. A. O. Thomas ...n wa niyara fun iwọn iṣẹju mẹdogun, ati pe ...gbogbo igba ti on wa nibẹ. Anduru ko ṣeṣi ...ọlọhun ọrọ kan rara, iyoku di iregbe, fọnfọn ...ọn, asun ma parada ni t'igi aja; orun ṣa ni ...ru nsun. Paripari ọrọ A. O. Thomas (ẹlẹri ...n James George papa pe wa si kotu ko ...kin wọn lẹhin i ni pe lati ọjọ kẹtala oṣu ...ember ti "Ọrọ" ti lu Anduru, titi di ogun'jọ ...kan, ilẹ ọjọ kan ko mọ, ki on ma lọ si le ...i pe ni gbogbo akoko nwọnyi lakaye ori rẹ ...tobẹ rẹ to ṣe pe isọkusọ lo nsọ lojojumọ, ...i iye igba to nja ijakadi lati bẹ lu 'lẹ lati ...erese pẹtẹsi ile rẹ.

... Orişadipẹ Ọbasa jẹri pe nijọ ti "Ọrọ" lu ...u, nwọn ranṣẹ pe on. Fun odindi ọjọ ...lẹhin na, lakaye rẹ daru patapata. Ṣugbọn ...o kẹrin lọ o bẹrẹ si ri alafia titi oju rẹ fi wa 'lẹ ...la. Loya ẹlẹjọ ta ko o wọn-nle, o si ni on gba pe l' akoko ti Anduru wipe on fẹ wo Baba lọ si Idibo, ko mọ ohun to nsọ.

Mrs. M. W. Davies jẹri pe ori Anduru wa nilẹ nigbati on fi ọwọ si *Codicil* gẹgẹ bi ẹlẹri.

Lẹhin ti nwọn tun pade ẹjọ ni Loya Ajasa sọ ni Kotu pe on ki yio pe ẹlẹri mọ, nitoripe oku ẹjọ patapata ni awọn nro.

Onidajọ agba, His Honour Sir Ralph Combe wa t'ẹnu b'ọrọ, o ni o da on l'oju gbangba pe Anduru ko le ṣe ohunkohun nitori lakaye rẹ daru l'akoko ti nwọn wipe o ṣe *Codicil*. Onidajọ ni o ya on l'ẹnu lati ri pe James George to duro ni idure Loya fun Anduru, to si pe ara rẹ ni ọrẹ rẹ, ko le bere gbolohun ọrọ kan pere lọwọ Anduru pe, kilo ṣe to fi wipe on fẹ fi Afa Ogunbiyi dipo Afa Evan Williams gẹgẹ bi Baba Isiku, to si fẹ gbe gbogbo dukia Ile, ona, oko ati owo bi ẹgberun ponwun ọna mẹwa £10,000 to fi fun ọmọ mẹfa ri fun ọmọ kanṣoṣo. Nitorina, on sọ *Codicil* na di oku, ki awọn Loya si gba owo iṣẹ wọn ninu ogun Anduru.

Gbogbo Ilu, ẹrọ re o! Ẹlomiran le wipe ti ko ba si ẹjọ yi boya ọpọ lọpọ enia ni ki ba ti mọ pe "Ọrọ" lu Anduru, ati pe lakoko amodi rẹ, igba pupọ le nhuwa bi ẹniti nkan kọlu.

Ohun itiju nla ni eyi jẹ fun ọmọ Enia Dudu lo aṣiri aisan baba wọn di ohun ti gbogbo aiye gbọ, ti gbogbo aiye mọ. Ọrọ ebu lo jẹ pẹlu. Ṣugbọn tani a ba ri ba wi, boyẹ ni awọn to ṣe Iwe Aramu Ẹjọ ko nṣe Mrs. Comfort Agbe rara, bẹni ko nṣe ti Florence Banjoko olutọju Adenikẹ ọmọ kekere ti nwọn fi oruko rẹ p'ẹjọ keji Mrs. Agbe.

Mrs. Agbe fẹran baba rẹ pupọ ju ẹniti o le fẹ lati tu aşiri amodi rẹ sita, bẹni Ọmọṣalewa pẹlu, ẹniti a ngbọ oruko rẹ nigbakugba, papa l'akoko ti edekoyede wa larin Baba rẹ pẹlu Ṣọṣi *Bethel*. Ṣugbọn ewo ni şişe nigbati ogun ọmọ mẹfa ma di ti ọmọ kanṣoṣo?

Ninu ẹri rẹ, Mr. James George sọ fun wa pe a-wa-moto kan (*Motor Car Driver or Chaffeur*) ni Anduru ran wa pe on n'ile ni ọjọ kejidilogun oşu *September, 1923*, njẹ bi eyi ba ri bẹ nitọtọ, kini ṣe ti ko pe a-wa-mọtọ na, ko wa jẹri ni Kotu? Ki o si wa sọ bi ọsan ni Anduru ran on si James George ni tabi oru, ati ẹniti o wa lọdọ rẹ lakokona.

Ẹwẹ, James George tun sọ fun wa pe nigbati on de 'bẹ nijọ na, on ba Afa Ogunbiyi ati awọn ẹlomiran niyara; nigbati Anduru si ni ki gbogbo wọn jade, ti nwọn si njade lọ pẹlu Ogunbiyi, Anduru ju'wọ si Ogunbiyi pe ki o duro. Iyẹn ni pe Ogunbiyi ko mọ ohun ti James George wa şe nibẹ lọjọ na, nitorina o fẹ lati jade niyara pẹlu awọn iyoku, ki Anduru to da a duro lojiji, nitope Ogunbiyi nikan wa ki Anduru ni ti rẹ ni, ko ba ọrọ ati joye Baba Isiku ninu *Codicil* wa.

A ko wipe James George npurọ ojukoju, ṣugbọn **dajudaju, nigbati Ogunbiyi de ile Anduru ni ọjọ kejidilogun oşu September, 1923, ko to wọ iyara**

ki Anduru papa, James George ni Ogunbiyi koko bere bi o ti de tabi koi de ; gbara ti James George si de, ti awon mejeji ko si iyara, Ogunbiyi ni ẹniti o le gbogbo awon to wa ni iyara jade ko nṣe Anduru. Eyi fihan pe adehun kan l'aşiri ti wa larin James George ati Ogunbiyi tẹlẹ, nipasẹ ọrọ *Codicil* yi ; bi bẹkọ, nigbati o şe pe James George nikan şoşo ni Anduru ranşẹ pe ni ọjọ kejidilogun oşu *September* 1923, ( iyẹn to ba ranşẹ pe e rara ) ti ko ranşẹ pe Ogunbiyi pẹlu, kini Ogunbiyi wa şe nile Anduru ni ọjọ na gan, to si de bẹ tan, to nbere bi James George ti de tabi koi de.

Ibaşepe Anduru papa lo ranşẹ pe Ogunbiyi gẹgẹ bi James George ti wipe o ranşẹ pe on, Ogunbiyi ki ba ti fẹ fi iyara silẹ l'ojo na bi awon iyoku, ki Anduru to şẹşẹ ju ọwọ si i pe ki o duro, gẹgẹ bi Alọ ti James George pa.

Njẹ Anduru lo ha le awọn ọmọ rẹ jade kuro n'iyara ni ọjo kejidilogun oşu *September*, 1923? Agbẹdọ. Oniko rara, nitori ko le sọ ohunkohun lakoko na. Ogunbiyi lo le wọn jade, on na lo si koko de ni ọjọ kini ati ọjọ keji to nbere James George.

Talo le gbagbọ pe lati ọdun-mọdun ti Mr. James George ti nşe iwe agbaşe ogun-ologun, o le şe irufẹ *Codicil* abami to ni Anduru bẹ on şe yi lai bere ohunkohun lọwọ rẹ ?

Ka wipe otitọ ni Anduru tilẹ bẹ James George ni *Codicil* şe ninu eyiti o gbe ogun ọmọ mẹfa fun ọmọ kanşoşo, bi James George ko tilẹ ni ironu tabi lakaye ( *discretion* ) de ibiti o le bere idi iyipada na lọwọ Anduru, ki lo ran Ogunbiyi l'ẹnu pọ bi aşo ti on papa na ko fi le bere ? Odidi Afa Olorun ati Archdeacon of Lagos nlọwọ ninu ki a gbe ogun ti a pin fun ọmọ mẹfa ni oşu *July* 1923 pelu ẹgberun poun ọna mẹwa ( £10,000 ) lai ka ọpọlọpọ Ile, oko ati ohun işura miran fun ọmọ kanşoşo lainidi ni oşu meji pere lẹhin na, ti on, gẹgẹ bi ojişẹ Olorun, ko si le wadi ẹşẹ wo ni awọn ọmọ iyoku ti şẹ baba wọn tobẹ ti o fi fẹ sọ wọn di ẹdun arinlẹ bayi ; Ogunbiyi ko le bere, şe bi nwọn ti fi ọmọ kanşoşo rọpo ọmọ mẹfa ninu *Codicil* ni, nwọn şe fi on papa rọpo Afa ẹlẹgbẹ rẹ Rev. Evan Williams, ti oku Anduru koi tutu ni 'koto, ti Ognubiyi ti sure kita-kita lọ gba powun mẹrindiladorin, şile mẹtala ati kobọ mẹrin £66. 13. 4. owo ti James George yọda fun un ninu *Codicil*.

Ohun itiju patapata lo ni lati jẹ fun gbogbo Ijọ C. M. S. to wa ni ilu Nigeria lati ri i pe a nba odidi Archdeacon wọn l'Eko nidi işekuşe bayi, ti Archdeacon of Lagos nyọ fẹrẹ lati şe Baba Isinku Olobinrin pupọ ( *Polygamist* ) mẹmba Şọşi Bethel lo si gba £66. 13. 4. bi owo işẹ rẹ lati pin ogun larin awọn ọmọ alarede ati ọmọ Abisode, lati pin fun Alarede papa ati awọn Orogun rẹ The Venerable Archdeacon of Lagos !

A fẹran Afa Ogunbiyi pupọ, a ko fẹ işubu rẹ, nitoripe ẹtẹ awo ni ẹtẹ ogbẹri. Ohun isin nla nla lo njẹ fun wa ibi orilẹ ede lati ma ri Ẹnia Dudu ni ipo giga, ipo ọla ati ipo owọ nitoria, Afa T. A. J. Ogunbiyi ati Ọgbẹni James George, ẹ so di ọwọ nyin, nitoripe nijọ kijọ ti a ba tun gbọ orukọ nyin nidi nkan rederede bayi, "agan a bẹ ki Polisi to de."

## KINI COLONEL MOORHOUSE TILẸ NFI ARA EKO PE ?

Ni Satide ijẹjọ Mr Birrel-Gray ( *Resident of the Colony* fi iwe ranşẹ si awọn mẹdogun kan l'Eko pe ( Colonel Moorhouse ) fẹ ba wọn sọro ni ile rẹ ni *Tuesday* ijarun ni agogo mẹwa, nipasẹ Arẹmọ Oba Ilu Oyinbo to nbọ.

Pupọ ninu ẹniti o yẹ ki o wa si ipade na ni a ko fi iwe pe. pupọ ninu awọn ti a si fi iwe pe ni ko yẹ ki a pe sibẹ.

Ohun kini ti a kokọ fẹ bere ni pe talo fun Colonel Moorhouse ni orukọ awọn ti o pe sibẹ ; ekeji pe, ni ilu Oyinbo ibiti on papa ti wa, bẹni nwọn npe enia jo ti gbogbo awọn ti a pejọ na si nfi ara wọn jẹ oye lati şe oju Ilu nigbati Ilu ko ran wọn nişẹ ?

Dr. Ọbasa dide o ni on pinnu pe ki gbogbo awọn ti a pe si Ipade jẹ oye Aşoju Ilu fun Arẹmọ Ọba ( *Committee* ). O ha gbọ iru nkan bẹ ri, nibiti enia kan nfi ara rẹ joye lẹgbẹ pẹlu awọn to ku, laije pe ipade gbogbogbo ( *Public Meeting* ) lo yan nwọn ?

Lọya Ajasa dide o ni Dr. Randle ni o yẹ ki o şe alaga ( Chairman ) fun *Committee* na, nitori on ni aşaju Ẹgbẹ l'Eko, *Leader of Society in Lagos* şugbọn o gbagbe lati sọ bi Aşiwaju Gunbe ni Dr. Randle jẹ ni Eko ni tabi ti ẹgbẹ Alaşi...

Ẹnikan tun dide, oni ki Lọya Moore ati Lọya Alakija şe akọwe (*Secretaries*). Bẹni nwọn şe gbogbo rẹ juju titi Ipade fi tuka.

Bi Colonel Moorhouse ko ba mọ pe gbogbo ... ti nwọn je ni ile on yẹn ko tẹ Ilu l'ọrun, iyẹn ... lasan lo wa ni ipo to wa, ko mọ ohun ti Ilu ... yatọ si eyiti Ilu ko fẹ.

A o fi Ifẹ pẹlu Ayọ pupọ pade Arẹmọ O... bakanna, şugbọn ni ti wa, gbogbo awọn to sure ... joye "Atipako" lati ti Ilu ni ipakọ kiri ni ... Colonel Moorhouse, apọ ara wọn ni nwọn jẹ ... na si *because the principle is eggregiously wrong*. *More anon.*

Emi ni tinyin nitotọ.

ATARI AJANAKU.

### *FROM THE EDITOR'S OBSERVATORY.*

**While the grass is growing, the horse is starving!**

Such is the condition in which a thousand and one land-owners whose several pieces of this real property have been acquired by the Government at Yaba, 4 months ago find themselves. Up till the present writing, we are not aware of any attempt on the part of the Government to pay owners their compensation; although the acquisition work it is stated has been taken in hand with lightning rapidity in that region; it need hardly be said that a good number of this people has been looking in vain for the prompt payment of their dues like the proverbial Tantalus.

It is hoped the Government will do away with official red tape and so fulfil their obligations in time for "Hope deferred maketh the heart sick."

**"My learned Friend"——**

On appointment, the Honourable the First Lagos Member (Mr. Shyngle) paid a visit to Mr. Baddeley, the New Chief Secretary to the Government a few days ago; it so happened that the New Chief Secretary belongs to the talking profession and that both he and the honourable gentleman are members of the same Inn-Middle-Temple.

---

31, Marina, Lagos,
Nigeria, 5th January, 25.

Dear Shyngle,

With reference to your letter of yesterday on the subject of a Joint Committee for the purpose of giving a hearty welcome to His Royal Highness the Prince of Wales on his arrival in Nigeria, this is to inform you that I have submitted your letter to my colleagues.

I am requested to inform you that we are quite prepared to co-operate with you, as when we started the movement, several of the names were invited to our first meeting. It is felt that too large a Committee for the purpose for which we are to meet would be unwieldy; and that the number be reduced to eight on either side, and that Messrs. Herbert Macaulay C.E., and Adamu Animashaun shall not be included in the eight.

It is considered necessary to limit the number to eight as our Sub-committee consists at present of eight members who have already taken steps in the matter and have seen His Excellency the Governor.

The names of the Sub-Committee referred to are:—The Hon. Kitoyi Ajasa, Hon. S. H. Pearse, Dr. O. Obasa, Messrs P. J. C. Thomas, C. J. Da Rocha, A. Alakija, E. S. Ikoli and myself.

If this meets with your approval it is proposed that the meeting shall take place in one of the Committee Rooms of the Glover Memorial Hall at 5.30. p.m. on Wednesday the 7th instant.

With kind regards.

Yours faithfully,
*(Sgd)* JOHN RANDLE.

**Reply.**

1, Phoenix Lane,
Lagos, January 8, 1925.

Dear Sir,

I am directed by my committee to acknowledge the receipt of your letter of the 5th instant addressed to our Chairman the Hon. J. Egerton Shyngle, and to point out that the previous *pourparlers* had reference only to a conference which was suggested with the object of discovering a working basis or some *via media* for co-operation or united action for the Public arrangements for the reception of His Royal Highness the Prince of Wales and did not contemplate the idea conveyed by your letter under reply that such a Conference of delegates should at once constitute the "Joint Committee" for such reception.

I am to add that under the circumstances, but more particularly in consequence of the condition peremptorily stipulated by your colleagues and yourself—conditions which my committee regrets inability to approve of because they are lacking in breadth of outlook—my committee is persuaded that no useful purpose will be served by any further consideration of the matter.

Yours Faithfully,
(Sgd.) T. H. JACKSON,
*Hon. Asst. Sec. to the General Committee Reception of the Prince of Wales.*

Dr. John Randle, M.B., C.M.,
3, Marina, Lagos.

---

## JEHOVAH SHALOM PARISH.

It is gratifying to see the rapid progress Jehovah Shalom Parish is making under the pastorship of Revd. J. F. Ogunko.

The condition of the Church some years ago was deplorable but since this energetic minister has taken charge of the Church, things have changed for the better.

I wish the Church every success and for the Pastor power from above to carry on the great work before him.

AKI

---

## *IN MEMORIAM.*

Gone! but not forgotten
Green! will her memory be.

In ever loving and unfading memory of our dear Mother

ZENOBIA C. ỌMỌNIYI WILLIAMS

who resigned this mortal life for immortality on Saturday morning the 13th *January*, 1923, and passed into the bourne, from whose territory no traveller returns.

Mother thou art gone up on high
Resting in the bosom of Christ
Where all earthly cares of grief
Cease to trouble thy peace of mind.

HENRY OBAFUNMILAYO WILLIAMS.

Doherty's Compound,
Gbagi, Ibadan
13/1/25.

## OWE NI ẸSIN ỌRỌ.

[ Lati ọwọ AKIRIMANU.]

Si Oniwe-irohin "*Eko Akete*"

Mo ju ba o,

A fi itan kekere yi bẹrẹ ọrọ wa ti ọsẹ yi lati jẹ ki gbogbo wa mọ pe ohunkohun ti enia ba gbin ni yio ka afi pe bi a ti ṣe oni bẹ la o ṣe ọla. ọrẹ meji nbẹ ekini a ma jẹ "Bi ati ṣe oni ni a o ṣe ọla" ekeji a ma jẹ "Ti oni ni mo mọ" eyi ekini jẹ olowo o si ni ọmọ meji eyi ekeji jẹ talaka ko si ni ọmọ rara, nwọn mba ọrẹ nwọn lọ o si ni ọdun pupọ sẹhin ti ọrẹ ekeji "Ti oni nimo mọ" wa bẹrẹ si fi inu ro ika ti on yio ṣe fun ọrẹ on yi ki o le mọ pe Ti oni ni on mọ, nijọkan ọrẹ keji yi ranṣẹ si ọrẹ rẹ ekini pe ki o ran awọn ọmọ rẹ mejeji wa si oko lati wa gba iṣu fun. ṣugbọn ọrẹ ekini yi ti ko mọ ewu ti o wa ninu ọrẹ ran awọn ọmọ rẹ lọ ba ọrẹ ekeji yi, ki a ma fa gun lọ titi ọrẹ keji ti pese majele fun awọn ọmọ meji wọnyi nigbati awọn de o wa iṣu fun wọn o si fun wọn ni Ẹkọ merin ati ọbẹ ti o fi pese majele sinu rẹ nwọn si jẹ lai mọ nkankan, ṣugbọn nigbati nwọn pada de ile lai fa gun lọ titi awọn ọmọ mejeji yi ku nijọkanna, ọrẹ keji yi gbọ o si yara wa ba ọrẹ rẹ ekini yi daro iku awọn ọmọ rẹ mejeji ti o ku. Ọrẹ ekini yi dahun o si wi pe "ohun gbogbo ko ṣẹhin Ọlọrun" ati pe bi oruko on "Bi ati ṣe oni ni a o ṣe ọla" ọrẹ yi si lọ si ile, ko pẹ titi bi oṣu melo lẹhin iku awọn ọmọ meji yi babalawo Ọba ilu yi wa da ifa pe Ọba yio ku bi ko ba pa agbẹ fi o ni oko ti ọpẹ oko rẹ pin si ọna meje, lojukanna Ọba ran awọn ọmọ ogun rẹ pe ki nwọn ma wa ọpẹ ti opin si ọna meje; lai fa gun nwọn kan ọpẹ yi ni oko "Ti oni ni mo mọ" nwọn si mu to Ọba lọ Ọba si paṣẹ pe ki nwọn lọ fi pamọ, nigbana ni Ọba wa paṣẹ pe ki nwọn ma lu pa ṣugbọn ki nwọn fun ni majele jẹ ki o ku ki nwọn si ge ori re wa fun on lati ma fi ṣe itiṣẹ nwọn ṣe bẹ gẹgẹ. Eyi kọ wa pe idajọ ti a ba ṣe fun ọmọ ẹnikeji wa on na ni a o ṣe fun wa, "Owe ni ẹṣin ọrọ"—

***JOHN MUHAMMED BEYIOKU.***

As we have all known that "Character is the diamond that scratches every other stone" we deem it necessary to narrate for the benefit of our future generation the sketch of one of our prominent youngmen.

John Mohammed Beyioku was born at Asogbon quarter Lagos, on the 16th of February 1884 educated at Holy Trinity School Ebute Ero and St. Paul's Breadfruit School also at the C. M. S. Grammer School where he received liberal and fairly good education and have won honour from his teachers and School mates; a quiet and sympathetic man.

He started life under the Government Railway in 1903 whence he was transferred to the interior for prominent position owing to his straight forwardness and manly actions. He is a thorough Mohammedan but was trained up by our worthy townsman D. A. Taylor Esqre., a very close relative of his. He resigned the Government Railway in order to further his position in life and extend his knowledge both in clerical and literary lines. He joined one of the oldest and well known firm Messrs H. B. W. Russel & Co., Ltd., on the 29th November 1907 which he is still enjoying to-day as a Provision Storekeeper. Anyone who has the chance of coming in contact with him must of necessity admire his general deportment, social disposition and the cheerful attitude he always shows towards everybody who happens to go near him and have something to do with him. He has a strong belief in the following proverb:— "Money is welcome though it comes in a dirty cloud" and it is his daily expression that when we have gold, we are in fear; when we have none we are in danger. This however points out to us his ability, patience which he has encounterd for the past 18 years with excellent and unblemished character under Messrs H. B. W. Rusall & Co., Ltd.

One of the admirable features in his actions is that you can hardly see him in the big garb (I mean native gown when on business) unless at times his friends would induce him to be dressed after their own fashion.

If you have any doubt that this man is not entitled to all the eulogies that are bestowed upon him, just take a come round Broad Street near Imperial Hotel where you find him at Messrs H. B. W. Russell & Co., Ltd., Provision Store who is popularly known as "Enia Ṣoro" with his spectacles on, and he is even ready to attend any person who happens to call there and require his services. Furthermore we cannot but say that it is his wont to make the following expression, "I am a public servant as long as I am here." We wish Mr. Beyioku the best of luck, long lease of life and God speed.

Gẹgẹ bi a ti ṣe ileri a o sọ nipa igbesi aiye wa John Momodu Beyioku ẹniti adape rẹ "Enia Ṣoro" a gbidanwo lati ṣe bẹ nisinsinyi di ẹni ọdun mọkanlelogoji ni oṣu to nbọ, obi rẹ enia rere ti wọn ko si ni iwa agabagebe lọwọ; bi aṣa awọn obi ọmọde igbani nwọn lọ si ile iwe Ebute Ero lẹhin na nwọn tun to fun ẹkọ daradara nwọn tun ran lọ si ile we *bread fruit*, lẹhin eyi ki a le gbọdun Oyinbo yi nwọn ran lọ si ile iwe giga ti *C. M. S. Grammar* nibẹ ni ati ṣe akiyesi iru enia onisuru ti ọrẹ wa jẹ. Ni ọdun 1903 o bẹrẹ iṣẹ ni *Railway* nipa iwa ifarada rẹ nwọn ran lọ si ilu Oke ṣiṣẹ nibẹ pẹlu ipo giga laipẹ lẹhin eyi o ro lati ri aiye ni ọna miran o fi iṣẹ *Railway* Ọrẹ wa yi jẹ Musulumi faufau ṣugbọn Ọgbẹni David A. Taylor lo tọ dagba nitori ibatan timọ ni, lẹhin igba diẹ "Enia Ṣoro" wọ iṣẹ Russell ni ọdun 1907 eyi to nlọ bi ọdun gun nibiti o gbe wa di oni oloni ti kan si ẹnu're fun. Bi Ọgbẹni wa yi ti jẹ onisuru opọlọpọ enia lo ti lọ danwo, ṣugbọn bi ati bẹ la o ba ọla, iwa tutu rẹ ni gbogbo enia igba pupọ ni on papa ma nsọ pe "igbẹ l'owo aini owo lọwọ baba ijaiya, ohun ti a fẹ to suru rẹ lati ọdun mejidilogun ti ko si fi nkankan bikoṣe iyin ati ọla ni ọrẹ wa yi lọdọ awọn onişẹ rẹ. Ki o to le ri ninu riẹriẹ yio jẹ pe awọn ẹgbẹ rẹ nşe ase patak jẹpe pẹlu tulasi ni nwọn fi mu ko si awọn nwọnyi.

Emi ni tinyin nit

AKIRIMA

**J. C. VAUGHAN**

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun ikole fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ lorişirişi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awọn onişowo Irin Işẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ ọ.

## Ero ya wa ra

ADEBOYE ŞOLANKE Onişowo "Gbabiọgẹdẹ" nta Panu-kikọle ati kikanọkọ, Işo lorişirişi, Kọkọrọ (Işika) t'ilẹkun ati t'apoti lorişirişi, Atupa Ẹfalọwọ, Simenti, Ọda lorişirişi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun ẹrọ, ati Ọşan, ati Pakun ti Awo-ẹja lorişirişi, Awo ti awọn Aganyin fi nko Ẹja-şawa Pokun ati Ẹja Abọmafọ, ni Şọbu rẹ ni No. 4, Idunmagbo Street, (l'ebute Olowu) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street, (l'Anikantamọ) l'Eko.

O nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati Irin-işẹ Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.

Owo Ọja rẹ fanimọra. Ẹ lọ ra tiyin nibẹ.

**Coffins to suit your Taste.**

Coffins with Pillows, Shroud, Brass Edges, and Removable Lids, on sale at A. Kessler's Establishment, 7, Labinjo Lane, Lagos: also Gramophone Records, Gas-lamps, etc., etc.

Prices to suit you. No worry, prompt attendance. Make a call.

ẸNIKẸJI.

Aşọ oke to yanju mbẹ lọdọ Iya Afin Saamọta Ikẹ Ọlọrun fun tita, ọpọku ọyọku ni owo wọn, lọ bere ni 3, St. John *Street*, l'Eko, leti ile Johnson Agbejọro.

**GOOD MARKET.**

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop, 37, Odunlami Street, Lagos. The Specific acts like Magic: has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

**Cable Address:—**
"Steinafrik" HAMBURG

**E. H. STEIN & Co.**

**HAMBURG, Neurwall 10,**
**Hildebrandhaus.**
*AFRICAN MERCHANTS.*

***ALL INDENTS EXECUTED.***
for
English and Continental Goods
and
PRODUCE
Sold on Best Terms.

**Produce to Europe covered by Floating Marine Insurance Policy.**
*P. O. Box No. 503.*

Agent in Lagos:—
**Mr. Karimu Kotun**
3, DOSUNMU STREET.

**Ruby Plates! Ruby Plates!! Ruby Plates!!!**

BOON TO GOLDSMITHS

*Just arrived.*

Call at once and make your choice from:—

DURO THOMAS,
55, Massey Street, Lagos.

# A. Kessler,

**7, Labinjo Lane,**

**Williams Street,**

***P.O. Box 459***

**Highly Recommended :**

CRYSTALL LAGERBIER LÖWENBRAUEREI HAMBURG

THE

## Pilsener Beer

*"Crystall" Brand*

*Light & Sparkling*

**Per Case**

**32s.**

**Send for a trial case to-day and convince yourself of the first quality of this Beer.**

## White's Golden Female Tonic

A Splendid Remedy for Female diseases su as :—Barrenness, Weakness, Painful and Irregul Menstruation, Leucorrhœa (White's), Cram Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovari A tendency to Miscarriage etc., etc.,

**Made and sold only by** VICTOR WHITE Es 41, Offin Road, Lagos.

*N.B: Not obtainable elsewhere*

GBOGBONIȘE FUN OBINRIN

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, ijọ, Ed Aran, Oyun ti o ba lẹ bajẹ ati orișirisi arun mi ki jẹ ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE

"SHAKE THE BOTTLE."

## Ile Ita Egbogi ti Macaulay,

88, BROAD STREET.

Wabiwọsi orișirisi Egbogi lo ṣeṣẹ de l wa ni tita: awọn bi:—ogun Egbo orișiri ogun Ẹda, ogun arun așiri, ogun Arẹ ogun Onigbameji, ogun Aran orișirisi, og Lakuregbe, ati awọn ogun miran ti a ko mā to lẹsẹsẹ.

Ọpọku-ọyọku ni owo wọn, nwọn si jẹ idan.

Ọrẹ, ẹ lọ dan awọn Ogun wọnyi wọ ti a gbe nta wọn.

**Saccharine! Saccharine!!**

**Saccharine!!!**

500 Saccharine in packets on sale H. Campos's Shop, 37, Odunlami Stre Lagos.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.